# ÀWỌN ÒǸKỌ̀TÀN ÌTÀN-ÀRÒSỌ YORÙBÁ LÓRÍ ÌBÁṢEPỌ̀ TÓ WÀ LÁÀÁRIN OJÚṢE ÒBÍ ÀTI ÀÌSÁÀBÒ NÍ ORÍLẸ̀-ÈDÈ NÀÌJÍRÍÀ

**ỌMỌ́WÙNMÍ ỌMỌ́ṢỌLÁ IYAWE**
Department of Yorùbá
Federal College of Education, Abẹ́òkúta, Ogun State.
08060253131 / wunmiyawe1970@gmail.com

**OLÚFADÉKẸ́MI ADÁGBÁDÁ**
Department of Linguistics
Ọlábísí Ọ̀nábánjọ University, Àgọ́-Ìwòyè, Ogun State.
07031885801 / olufadekemiadagbada@gmail.com

**MOSES ADÉDIRE ADÉKÚNLÉ**
Department of Linguistics and Nigerian Languages,
Ọlábísí Ọ̀nábánjọ University, Àgọ́-Ìwòyè, Ogun State.
08055301327 adédire.adékúnlé@oouagoiwoye.edu.ng

**DOI : https://doi.org/10.5281/zenodo.20757224**

**Àṣamọ̀**
Ọkan lára ìṣòro tó ń gbógun ti ìdàgbàsókè àwùjọ wa ni àìsáàbò jẹ́, àìsáàbò yìí sì dàbí jẹjẹrẹ tó ń jẹ orílẹ̀-èdè Nàìjìrìà díẹ̀díẹ̀. Àwọn onímọ̀ lẹ́ka gbogbo a máa fojú eréfèé wo ọ̀rọ̀ ètò ààbò nípa dídárúkọ àìríṣẹ́ṣe, ìjákulẹ̀ ìjọba, èètò ìdájọ́ tó mẹ́hẹ àti àwọn yòókù bí i rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí okùnfà àìsáàbò ṣùgbọ́n amúkùn-ún ẹrù rẹ wọ́ lọ̀rọ̀ náà, ó ní òkè lẹ ń wò, ẹ kò wo ìsàlẹ̀. Nítorí náà, iṣẹ́ ìwádìí yìí tọ́ka sí ojúwòye àti ìhà tí àwọn òǹkọ̀tàn ìwé ìtàn-àròsọ Yorùbá márùn-ún kọ sí ọ̀rọ̀ ojúṣe òbí gẹ́gẹ́ bí ọ̀kan lára ọ̀nà àbáyọ sí ètò ààbò tó mẹ́hẹ ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà; *Atótó Arére, Ìrìnàjò Ìfẹ́, Ayé Dayé Obìnrin, Ọmọ Ẹni ò Ṣèdí Bẹ̀bẹ̀rẹ̀ ai Ṣóoróyè.* Iṣẹ́ ìwádìí yìí ṣàmúlò tíọ́rì ìbára-ẹni-gbé-pọ̀ wo lítíréṣọ̀ gẹ́gẹ́ bí ọ̀pá òdiwọ̀n. Ìwádìí fi hàn pé àwọn òǹkọ̀tàn ìwé ìtàn-àròsọ Yorùbá rí ojúṣe òbí gẹ́gẹ́ bí ọ̀kan gbòógì lára àwọn ọ̀nà àbáyọ sí àìsáàbò láwùjọ. Wọ́n ṣe àgbékalẹ̀ ìbáṣepọ̀ tó wà láàárín ojúṣe òbí àti ìwà àìtọ́ tó ń ṣe okùnfà àìsáàbò. Iṣẹ́ yìí fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé ì-báni-dáa-báni-débẹ̀, ẹ̀kọ́ àkọ́yege, jíjẹ́ àwòkọ́ṣe rere àti ìmúdúró ìgbéyàwó gan-an tó jẹ́ ojúṣe òbí ni ọ̀nà àbáyọ àkọ́kọ́ fún ìwà àìtọ́ láwùjọ. Iṣẹ́ ìwádìí yìí wá dá a lábàá pé ẹ̀kọ́ nípa ojúṣe òbí yẹ kó wà nínú kọ̀ríkúlọ̀ọ̀mù ilé ẹ̀kọ́ girama, òfin tó wà nílẹ̀ nípa ṣíṣe àti àìṣe ojúṣe òbí gbọ́dọ̀ múlẹ̀ láti dènà àìsáàbò tó ń pagi dínà ìdàgbàsókè orílẹ̀-èdè wa.

**Kókó-ọ̀rọ̀:** Ètò Ààbò, Àìsáàbò, Ìdàgbàsókè, Ìtàn-Àròsọ, orílẹ̀-èdè Nàìjíríà

## 1. Ìfáárà

Ọ̀rọ̀ ṣùnnùkùn tí ó gba kí á fojú ṣùnnùkùn wò ni ọ̀rọ̀ ààbò orílẹ̀-èdè Nàìjíríà nítorí pé ààbò ìlú àti àwùjọ ni ọ̀pákùtẹ̀lẹ̀ ìlọsíwájú àti ìdàgbàsókè ìlú. Ìdí nìyí tí ọ̀rọ̀ ààbò orílè-èdè yìí ṣe múmú láyà àwọn ọ̀tọ̀kùlú àti onímọ̀ káàkiri ẹka ìmọ̀. Bí ọ̀ọ̀dẹ̀ ò dùn, bí ìgbẹ́ ni ìlú rí, kò sí ọmọ tálákà tí yóò ròde ẹmu. Rọ̀gùnrọ́gún owó ló ń wọlẹ̀ sí ẹka ètò à àbò ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà láìsí ààbo kan tó yè kooro tí a lè fojú ú rí pàtó nítorí àìsáàbò wà lára ìṣòro gbòógì tí orílẹ̀-èdè Nàìjíríà ń kojú láti ọjọ́ pípẹ́ ṣùgbọ́n dípò kó rọ̀ lára ewé àgbọn, kokooko ló tún ń le bí eyín afọ́ọgun. Àwọn onímọ̀ bí i

Ògúnṣínà (1987) àti Adéyẹmí (2006) ti dá sí ọ̀rọ̀ ọ̀nà àbáyọ sí ìṣòro yìí tí púpọ̀ nínú wọn sì tẹnumọ́ okùnfà àìsáàbò léréfèé bí àìríṣẹ́ṣe, ìjákulẹ̀ àwọn adarí, ìjà ẹlẹ́yàmẹ̀yà, ètò ìdájọ́ tí kò pegedé, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ìṣòro Àìsáàbò ti pẹ́ ní orílè-èdè Nàìjíríà bí iná ori. Láti ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ tí àwọn òyìnbó aláwọ̀ funfun ti kó oríṣìí ẹ̀yà jọ gẹ́gẹ́ bí orílẹ̀-èdè Nàìjíríà ni ìṣòro àìsáàbò ti bẹ̀rẹ̀. Ọ̀rọ̀ àìsáàbò wá kúrò ní ohun tí ó ń bá orílẹ̀-èdè Nàìjíríà nìkan fínra. Èyí ni pé àrùn tí ó ń ṣe ogójì ló ń ṣe ọ̀ọ́dún, gbogbo ohun tó ń ṣe Abọ́yadé gbogbo Ọlọ́ya ló ń ṣe lọ̀rọ̀ àìsàábò jẹ́. Àwọn orílè-èdè tó lẹ́ran, nífọ̀n káàkiri àgbáyé náà ní ìṣòro yìí ṣùgbọ́n ìhà tí Nàìjíríà kọ̀ sí dídẹ́kun ìṣòro àìsáàbò ló mẹ́hẹ, tó sì yàtọ̀ sí àwọn orílè-èdè àgbáyé yòókù. Àìsáàbò ń wáyé nígbà tí ẹ̀mí, dúkìá, àti ohun ìní àwọn ènìyàn yálà àfojúrí, àbí àìfojúrí bá wà ní ipò tí ó léwu. Nígbà tí àwọn ènìyàn ò bá fi ọkàn tán ara wọn, ará yòókù, ìjọba tàbí àwọn ẹ̀ṣọ́ aláàbò láti fi ẹ̀mí tàbí dúkìá wọn dá wọn ní a ń pè ní àìsáàbò.

Ìwọ̀nba ni àwọn onímọ̀ pẹ̀ẹ̀ké lu ọ̀rọ̀ nípa ojúṣe òbí gẹ́gẹ́ bí okùnfà àti ọ̀nà àbáyọ sí ìṣòro àìsáàbò ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà. Nítorí náà, iṣẹ́ ìwádìí yìí wo ìmọ̀ràn àti àríwísí àwọn òǹkọ̀tàn ìwé ìtàn-àròsọ Yorùbá méje; *Atótó Arére, Ìrìnàjò Ìfẹ́, Omi Inú Ẹkù, Ayé Dayé Obìnrin, Ọmọ Ẹni ò Ṣèdí Bẹ̀bẹ̀rẹ̀, Ṣóoróyè, àti Ogé Ré mi fọ́* láti wo ipa tí ojúṣe òbí ṣíṣe ń kó nínú ìdènà àìsáàbò àti bí ojúṣe òbí tó mẹ́hẹ ṣe ń ṣe atọ́nà àìsáàbò ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà ní ìbámu pẹ̀lú èrò àwọn agbáterù tíọ́rì ìmọ̀ ìbára-ẹni-gbé-pọ̀-wo-lítíréṣọ̀ tí wọ́n fúnka mọ́ àkíyèsí lítíréṣọ̀ nípa ìhun àti ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ. Wọ́n gbàgbọ́ pé oníṣẹ́-ọnà aláwòmọ́ lítíréṣọ̀ ò gbọdọ̀ takété sí ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ nítorí pé lítíréṣọ̀ ni ìwògbè àwùjọ Ògúnṣínà (1987) àti Adéyẹmí (2006)

**2. Aáyan Ọ̀mọ̀ràn lórí Àìsáàbò ní Orílẹ̀-èdè Nàìjíríà**

Ohun tí ó máa ń sọ iṣẹ́ akadá di èyí tí ó dùn-ún wò ni àwárí àti gbígbé lé òṣùnwọ̀n àwọn onímọ̀ ìṣáájú láti pa obì kí á yọ àbìdun rẹ̀. Àìsáàbò jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ìṣòro tó ń bá àwùjọ wa fínra. Lóòótọ́ ètò ààbò orílẹ̀-èdè jẹ́ ojúṣe ìjọba gẹ́gẹ́ bí Onífádé, C., Imhonop, P. D. àti Urim, U. M. (2013: 54) ṣe sọ nígbà tó ṣàlàyé pé:

> Security is all encompassing condition which suggest that a territory must be secured by a network of armed forces, that the sovereignty of the state must be guaranteed by a democratic and patriotic government which in turn must be protected by the military, police and the people themselves: that the people must not only be secured from the external attacks, also from the devastating consequences of internal upheavals such as unemployment, hunger, starvation, ignorance, homelessness, environmental degradation and pollution cum social-economic injustices.
>
> (Ààbò jẹ́ ohun tí ó gbòòrò, ipò tó ní í ṣe pẹ̀lú kí ilẹ̀ àti àyíká wà lábẹ́ aabo Ológun, ki òfin ìdádúró orílẹ̀-èdè wa lábẹ́ àbò ìjọba àwaarawa àti àwọn mẹ̀kúnnù tó ní àfọkànsìn, eléyìí tóun náa gbọ́dọ̀ jẹ́ dídáàbò bò lọ́wọ́ àwọn Ológun, àwọn ọlọ́pàá, àti àwọn mẹ̀kúnnù fúnra wọn; ipò tí kì í ṣe ìgbàsílẹ̀ lọ́wọ́ kí ààbò wà lórí ewu ilẹ̀ òkèrè ṣùgbọ́n àti lọ́wọ́ ìpayà àtubọ̀tán àìríṣẹ́ṣe, ebi, ìyàn, àìlẹ́kọ̀ọ́, àìrílégbé, àti àwọn ewu àyíká tó tara òórùn àti àìsídájọ́ jáde.)

Pẹ̀lú àlàyé Onífádé et al (2013) yìí, ìpèsè ààbò jẹ́ ojúṣe ìjọba àti àwọn aláṣẹ tó wà ní abala ètò ààbò ṣùgbọ́n àwọn onímọ̀ yìí fi kún un pé ààbò gbọ́dọ̀ máa wá láti ọwọ́ àwọn ọmọ orílẹ̀-èdè náà nítorí pé ènìyàn gan-an ni ojú ìjọba. Nítorí náà, gbogbo ènìyàn àwùjọ ni ọ̀rọ̀ ààbò orílẹ̀-èdè yẹ kó jẹ lógún. Ní pàtàkì jù lọ, àwọn ohun tí àwọn onímọ̀ yìí kà kún ohun tó ń ṣe okùnfà ààbò tó péye ní orílẹ̀-èdè kan dára tó ní Nàìjíríà. Àwọn nǹkan bí ìdáàbòbò mẹ̀kúnnù lọ́wọ́ ebi, àìríṣẹ́ṣe, ìyàn, àìlẹ́kọ̀ọ́, àìrílégbé, ìjàmbá ọṣẹ́ ohun àmúwá Ọlọ́run, òórùn àti àwọn àìṣedéédé nínú ìdájọ́ tó ń fa

rúkèrúdò láwùjọ. Àwọn nǹkan yìí gan-an ni ó ń fa àìsáàbò nítorí pé àwọn àìsáàbò àtọ̀húnrìnwá kò fi gbogbo ara da orílẹ̀-èdè Nàìjíríà láàmú bí àwọn àìsáàbò abẹ́lé. Ohun tó kàn kù tí a lérò pé ó yẹ kí àwọn onímọ̀ yìí fi kún èrò wọn nípa ààbò ni ojúṣe òbí lórí ọmọ nítorí pé ìdílé ni àwùjọ tàbí orílẹ̀-èdè tí ń bẹ̀rẹ̀. Ilé tí a bá sì fi itọ́ mọ ni, ìrì ni yóò wó ó. Ọmọ tí a fi sílẹ̀ tí a kò tọ́, ọmọ ọ̀hún ló máa gbé ilé tí a kọ́ tà. Ní pàtó, ìdàkejì gbogbo ohun tí wọ́n sọ yìí ni a ń pe àìsáàbò.
Udoh (2015) náà ki àìsáàbò báyìí:

(Àìsáàbò ni ipò tí ẹ̀mí àwọn èniyàn wà nínú ewu àti ìpalará. Ìfoyà tí èniyàn ń ní nígbà tí wọ́n bá wà nínú àìsáàbò nígbà tí èniyàn bá fúyẹ́ tàbí tó wà nínú àìsáàbò) Èyí ni pé àìsáàbò ń wáyé nígbà tí èniyàn ni orílẹ̀-èdè bá wà nínú ewu tàbí ìpalára àti gbogbo àwọn ìmọ̀sílára tó máa ń tí ara àìsáàbò jáde. Nítorí náà, tí kò bá sí ààbò, gbogbo èniyàn ni afurasí tí a kò lè fi ọkàn tán nítorí pé ìgbàkúùgbà ni ìpalára lè dé sí ẹ̀mí tàbí dúkìá èniyàn. Fún ìdí èyí ó ṣòro láti gbé nǹkan rere ṣe bí ààbò kò bá sí. Omede (2012: 315) dá sí ọ̀rọ̀ nípa àìsáàbò pé:

> Unemployment, bad governance, lack of quality education or training, lack or inadequate basic infrastructures, corruption and corrupt practices of government officials, perceived victimization, arrant poverty in the midst of affluence, ethnic superiority, religious superiority, domination and exploitation, materialism and display of it with impunity etc...
> (Àìríṣẹ́ṣe, ìṣèjọba tó mẹ́hẹ, àìsí ẹ̀kọ́ tó yè kooro, àìsí àwọn ohun amáyédẹrùn, ìwà ìbàjẹ́ àwọn òṣìṣẹ́ ìjọba, ìrẹ́nijẹ, ìṣẹ́ tó peléke nínú ọ̀pọ̀, ìjẹgàba, ẹlẹ́yàmẹ̀yà, ẹlẹ́sìnjẹ̀sìn, ìjẹgàba àti ìyanijẹ, ìṣàfihàn ọrọ̀ àti ọlá lá awon eniyan lójú àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ...)

Gbogbo ohun tí Omede (2012) tọ́ka sí yìí ló jẹ́ ojúṣe ìjọba ṣùgbọ́n èrò tiwa nínú ìṣẹ́ ìwádìí yìí ni pé bí a bá dẹ igbó kan tìtí tá ò rí nǹkan pa, ó yẹ kí a tún ìrìnàjò ẹni tọ̀. Nígbà tí a ti ìjọba, tí ìjọba kọ̀ láti mira, kí ló dé tí a kò mú ọ̀nà mìíràn pọ̀n? Àyàfi tí a bá fẹ́ máa fi ẹ̀kọ tan iná fúnra wa ló kù, àtìjọba àti mẹ̀kúnnù ló gbọ́dọ̀ kópa nínú fífi òpin sí ìṣòro àìsáàbò nítorí ẹja gbígbẹ tí kò ṣeé ká ni àwọn ọmọ tí òbí kò ṣe ojúṣe lórí wọn lati kékeré fún àwùjọ. Irúfẹ́ ọmọ bẹ́ẹ̀ náà sì máa dàgbà láti ṣe abiyamọ irúfẹ́ ọmọ wo wá ni ọmọ bẹ́ẹ̀ fẹ́ bí? Èyí ni Omede (2015) rí tí òun náà fi tún èrò rẹ̀ pa pé ìwà ọmọlúwàbí, ẹ̀kọ́ ilé, ẹ̀kọ́ ẹ̀sìn àti ìfọ̀rọ̀-ro-ara-ẹni-wò gan-an ni ọ̀nà àbáyọ sí ìṣòro àìsáàbò ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà.

Àkọ́kọ́ ná, Omede (2012 ṣe àlàyé àwọn ohun tó ń fa àìsáàbò àti bí ojúṣe àwọn tó wà lẹ́nu àṣẹ ìjọba ti mẹ́hẹ. Yàtọ̀ sí èyí, ó tún tẹnumọ́ ojúṣe ìjọba àti àwọn Ológun dáadáa nínú ìmọ̀ràn àti àbá rẹ̀ ṣùgbọ́n nígbà tí ó di ọdún 2015, ó rí i pé agbára kò ran ọ̀rọ̀ àìsáàbò mọ́, ó ti kúrò ní ogun àfibọn àti agbára jà. Ó ti di ogun ọgbọ́n pátá poo. Ìdí nìyí tí òun náà ṣe dábàá, ẹ̀kọ́ ilé, ẹ̀kọ́ ìwà ọmọlúàbí àti ẹ̀kọ́ ẹ̀sìn gẹ́gẹ́ bí ọ̀nà àbáyọ. Bí a kò bá sì ní fi dúdú pe funfun, iṣẹ́ àwọn òbí ni èyí nítorí pé nínú ìdílé ni àwùjọ ti bẹ̀rẹ̀. Èyí ni iṣẹ́ yìí ṣe lérò pé ó ṣe okùnfà àbá Omede (2012) yìí láti máa tẹnu mọ́ dídẹ́kun àìṣe ojúṣe òbí, dídẹ̀kun àìsíríṣẹ́ṣe fún àwọn ọ̀dọ́, títẹnumọ́ ẹ̀kọ́ ilé àti ìwà ọmọlúàbí àti àwọn ìlànà mìíràn. Eléyìí náà ló bí àmúlò lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ tí iṣẹ́ yìí gùn lé láti wagbò dẹ́kun àìsáàbò láwùjọ wa nítorì pé bí a bá fẹ́ pa igi run, ewé àti igi kọ́ la a gé, egbò rẹ̀ la máa wà. Àìṣe ojúṣe òbí gan-an ni gbòǹgbò àìsáàbò ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà.

## 2.1. Ojúṣe Òbí lórí Ọmọ

Nínú iṣẹ́ yìí àti àwọn àwárí tí a ti ṣe, iṣẹ́ òbí ju kí ó ṣe ọlọ́kọ̀ ọmọ wá sílé ayé lọ; láti inú oyún ni ojúṣe òbí ti bẹ̀rẹ̀, yálà èyí tó mọ̀-ọ́n-mọ̀ ṣe tàbí èyí tí kò mọ̀. Abífárìn àti Bello (2014) là á mọ́lẹ̀ pé:

> Every parent has a parental responsibility towards the child. There is also a parental autonomy which stipulates that a parent has a fundamental right to raise his/her child free from government intervention unless the child health and welfare are jeopardised by the parent's decision.
> (Gbogbo òbí ló ní ojúṣe láti ṣe fún ọmọ. Òmìnira òbí tó fi lélẹ̀ pé òbí ní ẹ̀tọ́ láti tọ́ ọmọ rẹ̀ láìsí àyọnusí láti ọ̀dọ̀ ìjọba àfi bí òbí bá ṣe ìpalára ajẹmọ́ ìlera tàbí ìgbáyégbádùn sí ọmọ náà.)

Ìpalára kò gbọ́dọ̀ sí fún ọmọ lọ́nà kankan nítorí pé òun náà ni ẹ̀tọ́ tirẹ̀. Ìdí nìyí tí òfin yìí fi múlẹ̀ ní àwọn ilẹ̀ òkèrè ṣùgbọ́n tí kò rẹsẹ̀ walẹ̀ dáadáa ní àwùjọ wa níbí. Ọwọ́jà òfin àti ojúṣe ìjọba tí kò tó ló fa èyí, tí àwọn ènìyàn fi ń fi ẹ̀ṣẹ̀ ṣe ayọ̀. Àìṣe ojúṣe ìjọba nínú iṣẹ́ yìí a máa ṣokùnfà àìṣe ojúṣe òbí lọ́wọ́ nítorí pé awo ní gbé awo nígbọ̀wọ́, bí awo kò bá gbáwo ní ìgbọ̀wọ́; awo a máa tẹ́, awo á sì máa ya. Láìsí àníàní, àìṣe ojúṣe òbí dàbí àrùn jẹjẹrẹ ní orílẹ̀-èdè kan; díẹ̀díẹ̀ ló máa bẹ̀rẹ̀ kó tó di pé yóò bú yọ. Èyí ni àwọn orílẹ̀-èdè àgbáyé tó wo ṣàkun ọjọ́ ọ̀la fi tètè máa ń múra sí ọ̀rọ̀ àwọn èwe àti ọ̀dọ́ kí wọ́n tó deegun ẹja, kí wọ́n tó di ògbólógbòó tí apá kò ní lè ká mọ́ bí wọ́n bá ti gbópọn nínú iṣẹ́ láabi nítorí àìsí ìtọ́ju.

**2.2. Tíọ́rì Ìfojú-ìbára-ẹni- gbépọ̀-wo-lítíréṣọ̀**

Àwọn agbátẹrù tíọ́rì yìí wòye pé aṣàfihàn àwùjọ ni lítíréṣọ̀ nítorí pé nínú àwùjọ gan-an ni lítíréṣọ̀ ti bẹ̀rẹ̀, àwùjọ ni orísun lítíréṣọ̀ àti pé, àwùjọ ló fi ń mí tó sì ń gbé jáde. Gẹ́gẹ́ bí èrò Ògúnṣínà (1987), abala ìmọ̀ méji ni a papọ̀ di tíọ́rì ìfójú-ìbára-ẹni-gbépọ̀-wo-lítíréṣọ̀ yìí. Àkọ́kọ́ ni Ṣọṣíọ́lọ́jì nígbà tí èkejì jẹ́ Lítíréṣọ̀. Àpapọ̀ méjééjì ló di ṣọṣíọ́lọ́jì lítíréṣọ̀ tó ń tọ́ka sí abala ìbáṣepọ̀ ọmọnìyàn láwùjọ tó fara hàn nínú lítíréṣọ̀ yálà alohùn tàbí àpilẹ̀kọ. Lára wọn agbátẹrù tíọ́rì ìbára-ẹni-gbépọ̀ ni Hypolite Taine, August Comte, Herbert Spencer, Karl Marx, Emile Durkheism, Max Weber àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ògúnṣínà (1987:19) ṣàlàyé pé lítíréṣọ̀ àti àwùjọ kò ṣe é yà sọ́tọ̀. Ó tún tẹ̀síwájú pé a kò gbọdọ̀ fojú ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ wo ìbára-ẹni-gbé-pọ̀ àti lítíréṣọ̀. Máyàmí ni lítíréṣọ̀ àti ọmọnìyàn jẹ, bákan náà, a kò lè ya àwùjọ ènìyàn àti lítíréṣọ̀ rẹ̀. Ògúnṣínà (2006:7-8) tún ṣàlàyé pé kò sí bí a ó ṣe gbé iṣẹ́-ọnà kan kalẹ̀ tí a kò ní wo àwùjọ tí a ti gbé e jáde. Ó wá ṣe àfikún pé ṣọṣíọ́lọ́jì lítíréṣọ̀ a máa wo ìbáṣepọ̀ tí ó wà láàárín iṣẹ́-ọnà àti àwùjọ gẹ́gẹ́ bí èyí tí ó ní ìbáṣepọ̀ tí kò yí padà; tí ọ̀kọ̀ọ̀kan sì nípa lórí òmíràn.

A kò gbọ́dọ̀ gbàgbé pé, Hypolyte Taine (1828-1893), Robert, Escarpit (1968 àti 1971) àti àwọn mìíràn bẹ́ẹ̀ jẹ́ gbajúgbajà nínú àwọn agbátẹrù tíọ́rì ìmọ̀-ìfojú-ìbára-gbépọ̀-wo-lííréṣọ̀. Ohun tó jẹ Taine lógún ni abala àwùjọ tí iṣẹ́-ọnà aláwòmọ́-lítíréṣọ̀ fúnka mọ́ àti bí iṣẹ́ ọnà aláwòmọ́ lítíréṣọ̀ kò ṣe ní takété sí àwùjọ tó ti jáde wá. Èyí ni Ògúnṣínà (2006:6) rí tó fi ṣàlàyé pé;

> Literature is part and product of society. Its nature is essentially social. It has no independence from man for it is produced by people living together.
> (Lítíréṣọ̀ jẹ́ ohun tó dà pọ̀ mọ́ àwùjọ. Àbùdá ìrísí rẹ̀ jẹ mọ́ àwùjọ. Lítíréṣọ̀ kò lè takété sí àwùjọ nítorí pé àwọn ènìyàn nínú àwùjọ ló ṣẹ̀dá rẹ̀.)

Èyí ni pé lítíréṣọ̀ àti àwùjọ jẹ́ nǹkan tó jẹ wọnú ara wọn tí ó ṣòroó yà sọ́tọ̀. Kódà, oníṣẹ́-ọnà aláwòmọ́-lítíréṣọ̀ tó bá ń ṣẹ̀dá tàbí ṣe ìtúpalẹ̀ lítíréṣọ̀ tí kò bá ṣàkíyèsí àwọn abala àwùjọ tí iṣẹ́-ọnà bẹ̀ẹ̀ dá lé lórí kò tíì rí ọ̀rọ̀ sọ. Ìdí nìyí tí àwọn onímọ̀ kan ṣe pè é ní ìwògbè tàbí díngí tí a lè gbá wo àwùjọ kedere láti rí àṣà, èdè, ẹ̀sìn, ìgbàgbọ́ àti ojú-àmúwayé àwọn ènìyàn tó wà nínú àwùjọ. Èrò àwọn agbátẹrù tíọ́rì yìí bá àfojúsùn àwọn oníṣẹ́-ọnà aláwòmọ́ lítíréṣọ̀ mu pàápàá jùlọ àwọn

òǹkọ̀tàn iwé ìtàn-àròsọ Yorùbá tí a ṣà yàn nínú iṣẹ́ ìwádìí yìí nítorí pé àyípadà àìsáàbò tó ń pagi dínà ìlọsíwájú orílẹ̀-èdè Nàìjíríà ló jẹ wọ́n lógún nípasẹ̀ ìtẹnumọ́ ojúṣe òbí.

**3. Ìhà tí àwọn Òǹkọ̀tàn Ìwé Ìtàn-Àròsọ Yorùbá kọ sí Ojúṣe Òbí àti Àìsáàbò**
Gẹ́gẹ́ bí àgbékalẹ̀ àwọn òǹkọ̀wé nínú àwọn ìwé ìtàn-àròsọ ti àgbéyẹ̀wò, oríṣìí ọ̀nà ni wọ́n là kalẹ̀ tí ojúṣe àti ipa òbí le gbà dẹ́kun tàbí ṣe okùnfa àìsáàbò láwùjọ wa. Àwọn òǹkọ̀wé yìí jẹ́ aṣàfihàn àti aṣàtúntò àwùjọ nípasẹ̀ lítíréṣọ̀. Nítorí náà, wọn ya àwòrán àwùjọ sínú ìwé wọn lójúnà àti tọ́ka sí àwọn kùdìẹ̀-kudiẹ tó wà láwùjọ àti ọ̀nà àbáyọ wọn. Lára ọ̀nà tí àwọn òǹkọ̀wé náà tọ́ka sí ni; Ì-bá ni-dá a-bá-ni-débẹ̀, Ẹ̀kọ́ Àkọ́yege fún Ọmọ, Jíjẹ́ àwòkọ́ṣe rere fún Ọmọ, Ṣíṣe Ìmúdúró Ìgbéyàwó àti ìbágbépọ̀ òbí méjéèjì, ìpèsè ohun ìní àti àdúrótì fún ọmọ àti Ẹ̀kọ́ ilé.

**3.1. Àìsí Àṣà Ì-bá ni-dá a-bá-ni-débẹ̀:** Fogarty àti Evans (2009) ṣe àlàyé ọ̀nà márùn-ún tí bàbá ń gbà láti fi ojúṣe wọn hàn lórí ọmọ nínú mọ̀lẹ́bí. Wọ́n pé àwọn òté ìdámọ̀ náà ní 5 Ps. Eléyìí tí lẹ́ta P bẹ̀rẹ̀ gbogbo àwọn ọ̀rọ̀ náà lédè Gẹ̀ẹ́sì. Àwọn ọ̀nà máràárùn-ún nìyí; Participator/Problem-solver, (abánidáabánidébẹ̀/abánitánṣòro) Playmate (Alábàáṣeré ọmọ), Principled guide (atọ́mọsọ́nà), provider (olùpèsè), àti preparer (akọ́nilọ́rọ̀-bí-ìyekan). Bí a bá wo bí bàbá Àpèkẹ́ ṣe ṣe nínú ìwé ìtàn-àròsọ Ṣóoróyè. Bàbá Àpèkẹ́ ṣe àbẹ̀wò òjijì sí i nílé ẹ̀kọ́ ọmọ rẹ̀. Ì bá jẹ́ pé kò ṣe àbẹ̀wò òjijì yìí sí ni, òun náà ò bá tẹ̀síwájú títí dé oko ìparun gẹ́gẹ́ bí àwọn òbí Àmọ̀pé. Láti ìbẹ̀rẹ̀ ni bàbá Àmọ̀pé kò ti bẹ ọmọ rẹ̀ wò nílé-ẹ̀kọ́ nígbà tó wà ní ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀. Àti ìgbà náà tí ìyá rẹ̀ ti ń wá ọ̀nà àbùjá fún ọmọ yìí ni ó ti ń yán ọ̀rọ̀ náà léti bàbá rẹ̀ ṣùgbọ́n kò já a kúnra. Lóòótọ́ ni pé ìyá Àmọ̀pé ló jẹ̀bi jù nínú ọ̀rọ̀ yìí ṣùgbọ́n ì bá jẹ́ pé bàbá Àmọ̀pé náà ṣe àbẹ̀wò sí ọmo rẹ̀ tí kò sọ pé òun ti rán-an lọ sílé ẹ̀kọ́ nìkan ni, Àmọ̀pé kò bá tí di ṣóoróyè tí kò róyè mú délé. Òwe alágẹmọ ti bímọ tán, ti àìmọ̀ọ́jó kù sọ́wọ́ ọmọ̀ rẹ̀ kò ṣiṣẹ́ láyé òde-òní, àyàfi tí òbí náà kò bá fẹ́ ní ìfọ̀kànbalẹ̀ lọ́jọ́ ayé rẹ̀ ló lè tẹ̀lé ọ̀rọ̀ náà. Nítorí èyí, òbí gbọ́dọ̀ jẹ́ abáni-dáa-báni-débẹ̀ nínú ìgbòkègbodò ọmọ wọn. Àpẹẹrẹ mìíràn nínú àwọn àṣàyàn ìwé ni Fẹmóò nínú ìwé ìtàn-àròsọ *Ìrìnàjò Ìfẹ́.* Ó sọ pé:

> Ó ní semester kan péré ni bàbá òun sanwó rẹ̀, tí mọ̀mọ́ òun sì tiraka láti san *second semester*. Bí òun ṣe ń ràwé, ilégbèé, àti oúnjẹ kò kàn wọ́n mọ́. Bí òun ṣe térò ara òun pa nílé-ẹ̀kọ́ nùn-un. ( o.i 43)

Àwọn òbí Fẹ̀móò kàn bá a dá ilé-ẹ̀kọ́ lílọ ní, wọn kò bá a débẹ̀ rárá. Wọ́n lérò pé ọmọ àwọn ti tó ojú bọ́ ṣùgbọ́n wọn kò mọ̀ pé ìgárá ọlọ̀ṣà, ẹlẹ́gbẹ́ òkùnkùn àti alọnilọ́wọ́gbà ni ọmọ àwọn nílé-ẹ̀kọ. Ì bá jẹ́ pé Mágírẹ́ẹ̀tì náà dá ọmọ rẹ̀ dá ilé-ẹ̀kọ́ ni, tí kò bèèrè irú ọ̀rẹ́kùnrin tó ń bá rìn tàbí tó fẹ́ fẹ́ ni, Atinúkẹ́ náà ò bá bọ́há bí ìyá rẹ̀ ṣe bọ́há nìgbà tirẹ̀. Èrò Akínlabí ló hàn gédégbé nínú àyọlò yìí bí ó tilẹ̀ fi sí ẹnu asọ̀tàn ojúmilóṣe. Bákan náà, nínú ìwé ìtàn-àròsọ *Ọmọ Ẹni ò Ṣẹ̀dí Bẹ̀bẹ̀rẹ̀*, Fádíyà, ṣe àfihàn àwọn òbí Ìbíyẹmí tí kò fi sílẹ̀ nígbà kọ̀ọ̀kan. Gbogbo ohun tó nílò ni wọ́n fún un. Yàtọ̀ fún èyí, àdúrótì, àdúrà, ìkẹ́ àti ìgẹ̀ kò jẹ ọmọ yìí níyà. Ìdí nìyí tí kò fi ráàyè ṣe ìranù tàbí ní iyèméjì pé òhun máa dé èbúté ògo bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àkàndá ẹ̀dá ni ọmọ náà. Ì bá jẹ́ pé àwọn òbí ìyá àgbà tó gbé ọmọ sọnù nínú ìwé yìí tó padà di àbámọ̀ fún un nítorí pé kò lè bímọ mọ́ dúró tì í gẹgẹ́ bí òbí, tí wọn kò sọ òun àti àwọn àbúrò rẹ̀ di ẹni tó ń dá gbé, ọ̀rọ̀ rẹ̀ kò bá tí rí bẹ́ẹ̀. Ó ṣàlàyé bí àwọn òbí òun ṣe kùnà nínú ojúṣe wọn tó ṣe àkóbá fún òun pé:

> Ó ní alájàpá ni ìyá òun, kí ilẹ̀ tó mọ́, ó ti bá tirẹ̀ lọ. Ó ní bí ó bá sì lọ bẹ́ẹ̀, ó di alẹ́ pátápátá kí ó tó tún padà wọlé. Ìgbà tí yóò bá sì fi wọlé, àwọn ọmọ ti sùn. Orí tábìlì ni a ó bá owó oúnjẹ wa bí a bá jí ní ọjọ́ kejì. Ó fi kún àlàyé rẹ̀ pé, ẹ̀yìn odi ni bàbá òun ti ń ṣiṣẹ́ awakọ̀, àti pé agbégilódò ló ń wà. Ẹ̀ẹ̀kan lóṣù ni bàbá òun máa ń wálé, bí wọ́n bá sì ti wálé, àmukúdórógbó ọtí ni. *(Ọmọ Ẹni,* O.I. 51)

Kò sí ẹni tí a ó ò gbé gorí ẹṣin tí kò ní sọ ìpàkọ́ lùkẹ́. Kò sí ọmọdé ní ìpele ọ̀dọ́-mọ̀-ọ́n-yọ̀ tí àwọn òbí méjéèjì dà sílẹ̀ báyìí tí kò ní ní àbàwọ́n kan nínú ìwa rẹ̀. Bí kò wá ní ikun, ó lè wá ní kẹ̀lẹ̀bẹ̀ ṣùgbọ́n bí ọ̀kan kò ṣe ọ̀kan ṣá máa ṣe ni ṣá. Ìdí nìyí tó fi ráàyè ṣe ìrégbè tó ń kó ọkùnrin káàkiri ìgboro débi pé kò sí ẹni tó gba oyún lọ́wọ́ rẹ̀ nínú àwọn ọkùnrin náà. Ìdí nìyí tó fi bímọ tán, tó sì lọ ààkìtàn lọ ju ọmọ ọ̀hún sí. Nítorí èyí, òbí rẹ̀ dá a dá ẹ̀kọ́, eléyìí tó dára ṣùgbọ́n wọ́n kùnà láti bá a débẹ̀ eléyìí tó ṣe pàtàkì jùlọ.

**3.2. Àìsí Ẹ̀kọ́ Àkọ́yege fún Ọmọ:** Gẹ́gẹ́ bí a ṣe sọ ṣáájú, dandan ni kí ọmọ kẹ́kọ̀ọ́ dé ààyè ibìkan láti lè lajú sí ìwà tó tọ́ àti èyí tí kò tọ́ tó wà ní àwùjọ. Ẹ̀kọ́ dàbí ìṣínilójú. Ìdí nìyí tí àjọ UNICEF ṣe ń fọnrere rẹ̀ tí wọ́n sì pọn ọ́n ní dandan fún ìjọba ní ìpele gbogbo pé ọmọ gbọ́dọ̀ ní ẹ̀kọ, ó kéré tán jáde ilé-ẹ̀kọ́ girama kékeré kí ó tó lè fi igi gún un. Bí bẹ́ẹ̀ kọ́, ẹ̀ṣẹ̀ tàbí ọ̀ràn ni fún òbí ọmọ náà nítorí pé ó ti kùnà nínú ojúṣe rẹ̀. Nígbà tí ọmọ kò bá ní ẹ̀kọ́ yìí, báwo ló ṣe fẹ́ mọ̀ pé nǹkan yìí dára tàbí kò dára?

Nínú ìwé ìtàn-àròsọ *Omi Inú Ẹkù,* Débọ̀ Awẹ́ ṣe àgbékalẹ̀ ẹ̀dá-ìtàn Àlàó tí kò mójútó ẹ̀kọ́ ọmọ rẹ̀. Ó gba owó ilé-ẹ̀kọ ọmọ rẹ̀ lọ́wọ́ ọ̀rẹ́ rẹ̀, ṣùgbọ́n dípò kó san owó ilé-ẹ̀kọ́ ọmọ yìí, ó fi owó náà ta tẹtẹ́. Ọmọ náà gbìyànjú láti ṣe iṣẹ́ fúnra rẹ̀ láti rí owó, yẹyẹ́ tí àwọn ẹgbẹ́ rẹ̀ ń fi ṣe nílé-ẹ̀ko kò jẹ́. Eléyìí ló mú ọmọ yìí di olè tó jí àgbàdo lọ́jà, ọmọ yìí di ẹni tó ń lọ sí ilé tẹ́tẹ́ títa, ó di ẹni tó tẹ̀lé bàbá rẹ̀ lọ dáràn nípa títa òkú adìẹ fún àwọn ará ìlú gẹ́gẹ́ bí àyangbẹ ẹran ìgbẹ́. Yàtọ̀ fún eléyìí, ọmọ tó yẹ kó wà nílé-ẹ̀kọ́ di ẹni tó ń ṣe iṣẹ́ ọmọ ọ̀dọ̀ lọ́dọ̀ bàbá olówó kan. Èyí tó burú níbẹ̀ ni ìyá rẹ̀ tí òun náà fi ọmọ rẹ̀ sílẹ̀ nítorí pé ọkọ rẹ̀ kò hùwà dáadáa. Bí kò bá ṣe pé ọmọ yìí ń ṣiṣẹ́ ọmọ ọ̀dọ̀ tó fi ń tọ́jú ara rẹ̀, irú wọn ló máa ń di ọlọ́ṣà láàárín ìgboro. Fún ìdí èyí, ẹ̀kọ́ ṣe pàtàkì fún ọmọ. Ọmọ tí a bá kọ̀ tí a kò kọ́, kò ní han àwọn òbí rẹ̀ nìkan léèmọ̀, àwùjọ àti orílẹ̀-èdè máa jẹ 'omitooro' ìwà-àìtọ́ tó máa hù.

Bákan náà, Àìkí kọ̀ láti rán àwọn ọmọ rẹ̀ obìnrin nílé-ẹ̀kọ́ nítorí pé obìnrin ni wọ́n nínú ìwé ìtàn-àròsọ *Ayé Dayé Obìnrin*. Àìmọ̀kan-mọ̀kàn tirẹ̀ ló fi di bàbá ọlọ́mọyọyọ. Ó wá tìtorí èyí sọ àwọn ọmọ di eléyìí tó ń pín káàkiri nígbà tí agbára rẹ̀ kò ká ìtọ́jú àwọn ọmọ náà. Bọ́lá àti Ṣadé tó ti ń lọ sí ilé-ẹ̀kọ́ lọ́dọ̀ ẹ̀gbọ́n rẹ̀ di ẹni tí kò rílé ẹ̀ko lọ mọ́ nítorí àìgbọ̀ràn Àìkí. Bọ́lá tipasẹ̀ èyí  gboyún. Oyún tó ni fún Kọ́pà tí kò gbà ló fẹ́ gbé fún Ọnọ́rébù kí ìṣòro ti Ọnọ́rébù náà tó mu ún lómi. Kódà àwọn ọmọkùnrin tó lóun nífẹ̀ẹ́ láti tọ́ náà kò yà dáadáa ní ilé-ẹ̀kọ́. Àpẹẹrẹ èyí hàndé nínú àyọlò ìsalẹ̀ yìí:

> Adùnmídé àti Ọlámìídé tí àwọn ń kàwé náà ni wọ́n tún ka àkàtì ìwé yìí nítorí àìmóójútó òbí. Àíkí kò rówó tọ́ wọn dáadáa, kò tún ní àkókò fún wọn. Ọ̀sẹ̀ tí wọ́n dé ìpele kẹta ilé-ẹ̀kọ́ girama àgbà náà ni wọ́n darapọ̀ mọ́ ẹgbẹ́ òkùnkùn. Wọ́n ń ṣe ẹgbẹ́ òkùnkùn, wọ́n sì tún ń ṣe jàǹdùkú. Ìgbà ti Olúmìídé kú ni àṣírí yìí tó hàn sí àwọn òbí àti ẹ̀gbọ́n wọn.  *(Ayé Dayé Obìnrin*, O.I. 132).

Nítorí pé àwọn ọmọ yòókù jẹ obìnrin ni Àíkí kò ṣe jẹ́ kí wọ́n kàwé dé ààyè tó wù wọ́n. Ó bẹ̀rẹ̀ sí mú wọn káàkiri ilé àwọn ọ̀gá tí wọ́n ti ń kọ́ṣẹ́ pé kí wọ́n máa gbé ibẹ̀ kí wọ́n sì máa jẹun, àmọ gbogbo àwọn ọ̀gá náà ló kọ̀ pátápátá. Ọ̀gá Ṣadé tó gbà á sọ́dọ̀ ló tọ́ ọ ní ìwé dé ibi tó wù ú. Iṣẹ́ tí òǹkọ̀wé ní lọ́kàn nínú ìwé yìí hàn dáadáa. Ó fẹ́ kí á rí bí àìṣe ojúṣe òbí ṣe lè ṣe àkóbá fún ìlọsíwájú àwọn ọmọ tó jẹ́ ọ̀dọ́ tí ọjọ́ iwájú orílẹ̀-èdè yìí wà lọ́wọ́ wọn. Àwọn ọmọkùnrin tí bàbá wọn lóun ń tọ́ náà, kò rówó tọ́ wọn. Kò mọ ohun tí wọn ń jẹ débi pé yóò mọ ẹni tí wọn ń bá rìn. Eléyìí ló sọ àwọn ọmọ yìí wọ oko ìparun, tí wọ́n kò rógo lò. Ikú oró ni Ọlámìídé kú nígbà tí Adùnmídé di anùmádàròó nítorí ọ̀ràn tó ti dá.

Ládélé àti Músílì ló ba ayé Bọ́sẹ̀dé jẹ gẹ́gẹ́ bí òbí nínú ìwé ìtàn-àròsọ *Ogé Ré mi Fọ́*. Wọ́n sọ ọmọ náà di ẹyin tí ẹnikẹni kò gbọdọ̀ bá wí. Bí olùkọ bá bá ọmọ náà wí, ó dáràn àfi ìgbà tó bá fi iṣẹ́ sílẹ̀ kí ọkàn rẹ̀ tó balẹ̀. Kódà, wọ́n ti lé Bọ́sẹ̀dé kúrò nílé-ẹ̀kọ́ nítorí ìwà rẹ̀. Kò kẹ́kọ̀ọ́ dé ibi kan, tó fi lóyún fún Abíọ́nà. Ibẹ̀ ni ẹ̀kọ́ rẹ̀ parí sí. Eléyìí ló mú kí Bọ́sẹ̀dé di ìdàkudà tó jẹ́ pé iṣẹ́ òwò nàbì ló ń ṣe. Bí ó ṣe ń kúrò nílé ọkọ kan ló ń bọ́ sílé ọkọ mìíràn. Iṣẹ́ òwò pàrágà àti agbódegbà ẹrù àwọn olè ló ń ṣe. Abíọ́dún fi ọ̀rọ̀ gbá ẹ̀gbọ́n rẹ̀ lórí báyìí:

> Abíọ́dún sọ orí burúkú ọ̀rọ̀ sí ẹ̀gbọ́n rẹ̀ wí pé, àìgba ẹ̀kọ́ ló mú kí òun àti àwọn ọmọ rẹ̀ ó wà ní ipò burúkú yìí. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé baba kẹ́ wọn ní àkẹ́bàjẹ́, ṣebí baba kan náà ló tọ́jú àwọn méjèèjì ṣùgbọ́n ẹ̀kọ́ tí ẹ̀gbọ́n òun kọ̀ sílẹ̀ tí kò gbà ló gbé dé irú ipò ìbànújẹ́ tí ó wà lónìí yìí.   (*Ogé Ré mi Fọ́*, O.I. 52).

Ì bá jẹ́ pé Bọ́sẹ̀dé kàwé tó dé ipò tó yẹ kó dé, ì bá jẹ pé ẹ̀kọ-ilé dun Bọ́sẹ̀dé lára ni tabi Bọ́sẹ̀dé jẹ́ ọmọ tó gbẹ̀kọ́ bóyá òun náà ò bá rójú kọ́ àwọn ọmọ rẹ̀ tó di eegun ẹja sí àwùjọ lọ́rùn. Bí ọmọ kò bá ìró ìyá rẹ̀, ó di dandan kó bá ìpèlé. Irú ìpèlé wo ni Bọ́sẹ̀dé fi sílẹ̀ fún àwọn ọmọ rẹ̀. Nítorí náà, kò yani lẹ́nu pé àwọn ọmọ rẹ̀ di ìgárá ọlọ́ṣà tó ń da omi àláàfíà ìgboro rú kọ́wọ́ pálábá wọn tó ségi.

### 3.3. Àìjẹ́ Àwòkọ́ṣe Rere fún Ọmọ

Ọ̀kan lára "P" márùn-ún tí Fogarty àti Evans (2009) dábàá pé ó jẹ́ ojúṣe òbí lórí ọmọ ni Principled guide (atọ́mọsọ́nà). Bẹ́ẹ̀, Yorùbá bọ̀ wọ́n ní a kì í sọ pé a óò bẹ́ni lọ́rùn lójú ọmọdé, tí a bá sọ̀rọ̀ ìbẹ́nilórí lójú ọmọdé, lọ́rùn lọ́rùn ni wọ́n yóò máa woni. Ọ̀kan lára ọ̀nà tí òbí ń gbà kọ́ ọmọ láìmọ̀ ni ìṣesí àti ìhùwàsí wọn nínú ilé àti àwùjọ. Bí òbí bá ṣe ń ṣe lọmọ náà máa ń wò. Àwòkọ́ṣe là ń pe eléyìí, èyí sì ní ipa ribiribi tó ń kó nínú ìgbé-ayé àwọn ọmọdé àti ọ̀dọ́ láwùjọ. Nígbà tí àwọn òbí bá ya ìyàkuyà, kí ni a lérò pé ọmọ wọn máa yà?

Ládélé àti Músílì kò jẹ́ àwòkọ́ṣe rere fún ọmọ wọn. Bọ́sẹ̀dé tó jẹ́ olú ẹ̀dá-ìtàn nínú *Oge Ré Mi Fọ́* wo àwòkọ́ṣe àwọn òbí rẹ̀. Kò sí ẹni tí kò lè sọ̀rọ̀ sí. Kò sí ẹni tí kò le bú Pabambarì rẹ̀ ni ọkùnrin tó ń kó kiri tí àwọn ọmọ rẹ̀ náà sì ń wò ó. Eléyìí ni ó jẹ́ kí òun náà ni ọmọ tó ń wo ìṣe àti ìhùwàsí rẹ̀. Bẹ́ẹ̀ náà ni àwọn ọmọ Bọ́sẹ̀dé ń wo àwòkọ́ṣe rẹ̀ ti wọ́n fi di ọmọ pàpàǹlagi tó ń jalè nínú ìlú. Wọ́n jalè kò tó wọn mọ́, wọ́n tún di ìgán nínú àwọn tó ń jí epo rọ̀bì tà láàárin aginjù igbó níbi tí ọwọ pálábá wọ́n ti ségi. Ì bá jẹ́ pé ọwọ́ pálábá wọn ó ségi tí àwọn náà ń dàgbà tí wọ́n bímọ, ọmọ wọn náà a máa wo àwòkọ́ṣe wọn. A wá di pé àtọlẹ̀ dọ́lẹ̀ ni ti àdán, olubi a máa ṣubú lu olubi. Ọ̀nà yìí jẹ́ ọ̀kan tí àwọn ọmọ àlùsì ṣe pọ̀ káàkiri ní orílẹ̀-èdè yìí láàárín àwọn ọ̀dọ́ wa. Dandan ni kí wọ́n bá obìnrin irú wọn pàdé nígbà tí wọ́n bá ṣe eléyìí tí wọ́n bímọ. Ìwà-àìtọ́ á wá máa gorí ara wọn, àìsáàbò a sì máa ti ara eléyìí peléke láàárín ìgboro àti orílẹ̀-èdè.

### 3.4. Ìtúká Ìgbéyàwó àti Ìbágbépọ̀ Òbí Méjèèjì

Yorùbá bọ̀, wọ́n ní, àìsí nílé ológìnnì, ilé dilé èkúté. Olùrànlọ́wọ́ nipa iṣẹ́ ilé, nípa bùkátà àti ojúṣe lórí ọmọ ni "ọkọ àti ìyàwó nínú ìdílé" jẹ́ sí ara wọn. Rosenberg àti Bradford (2015:11) nígbà tí wọ́n ń gbẹ́nu Popenoe (1996) sọ ṣe àlàyé pé:

> Fathers are far more than just 'second adults' in the home, he says. "Involved fathers bring positive benefits to their children that no other person is likely to bring.
>
> (Bàbá kọja ẹni tó jẹ́ àgbà kejì lásán nínú ilé ó sọ pé, "Bàbá to tara bọ ojúṣe á mú àyípadà ọ̀tun àti àǹfààní wá fún ọmọ tí ẹlòmíràn kò lè mú wá fún ọmọ náà).

Àlàyé nípa ojúṣe bàbá yìí fi hàn pé àìsínílé ológìnní bàbá a máa sọ ilé di ilé èkúté. Kì í wá ṣe ilé èkúté nìkan, a máa sọ àwùjọ di ohun ẹ̀rùjẹ̀jẹ̀ fún àwọn ènìyàn nítorí pé àwùjọ tó bá ń dùn, ọmọ àlè ibẹ̀ ni kò tíì dàgbà. Olùbánidámọ̀ràn, alábàáṣeré, olùpèsè, akọ́nilọ́rọ̀-bí-ìyekan ẹni ni bàbá jẹ́ lórí ọmọ. Eléyìí kò sọ pé ìyá kò lè ṣe àwọn ojúṣe wọ̀nyí, ṣùgbọn ojú méjì kò lè jọ ojú mẹ́rin tó bímọ láéláé. Ìkekere mẹ́rìndínlógún ló wà ní ojú, tí ọ̀kan bá yọ kúrò, ààyè rẹ̀ máa ṣófo. Bẹ́ẹ̀ gan-an ni ọ̀rọ̀ bàbá àti ìyá gẹ́gẹ́ bí òbí rí nínú mọ̀lẹ́bí.

Bí ó ti wà ní lìkì náà ló wà ní gbàǹja. Síwájú síi, Štrbová (2004:17) fi èrò rẹ̀ ṣe àfikún àlàyé nipa pàtàkì òbí méjèèjì pé:

> Child needs both parents, especially due the differences between the genders, the mental selfhood of man and woman, who complement each other as two halves forming one whole unit. A child, who is, for any reason, brought up only by a father or mother, is literally lacking the second half. And this can originate to a miscellaneous life and personal complications.
>
> (Ọmọ nílò òbí méjèèjì, pàápàá jùlọ nítorí ìyàtọ̀ tó wà láàárín gẹ́ńdà méjèèjì, ìgboyà fún ti ọkùnrin, obìnrin ní tirẹ̀, ló ń ṣe àkópé ipa wọn gẹgẹ́ bí abala méjì tó ń ṣèdá odidi kan. Ọmọ tí bàbá tàbí ìyá nìkan bá tó máa ṣe àfẹ́kù abala kejì. Èyì sì lè ṣe okùnfà ayé tí kò pé àti ìnira fún un).

Bí ìyá tàbí bàbá ọmọ nìkan ló bá wà ní àyíká ọmọ nínú mọ̀lẹ́bí tó yẹ kó jẹ́ ibi ìfọ̀kànbalẹ̀, ibi ayọ̀, ààbò àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ fún ọmọ, ó dàbí ẹni tó ń lu àṣán kan bàtá ni. Kò lè dàbí kí òbí méjèèjì lọ́kùnrin àti lóbìnrin wà ní àyíká ọmọ nítorí pé ẹ̀kọ́ tí ọmọ ń rí kọ́ lára àwọn méjèèjì jọra wọn ṣùgbọ́n ìyàtọ̀ wà nínú rẹ̀, pàápàá jùlọ nínú àgbékalẹ̀ wọn. Bí a bá fojú èyí wo èrò àwọn òǹkọ̀wé ìtàn-àròsọ Yorùbá tí a lò nínú iṣẹ́ ìwádìí yìí, níjọ́ ìyá kú ni wúrà bàjẹ́, ọjọ́ tí baba bá ku ni díígí ọmọ wọmi. Kì í ṣe ọjọ́ tí wọ́n bá kú nìkan, bí ọmọ bá ṣe àfẹ́kù ìyá tàbí bàbá rẹ̀, ó máa ń sáábà yọ sílẹ̀ fún ọmọ náà gẹ́gẹ́ bó sẹ yọ sílẹ̀ fún Àlàbá, tó wá di pé abẹ̀bẹ̀ rẹ̀ ń fi ibi pẹlẹbẹ lélẹ̀ nígbàagba nínú ìwé ìtàn-àròsọ *Atótó Arére*. Ìyàwó kejì, Taibatu tí Búsàri bàbá Àlàbá fẹ́ fi aye sú Àlàbá. Kò jẹ́ kí bàbá rẹ̀ fún un ní ẹ̀kọ́ tó péye. Bó ṣe ń di iṣẹ́ rù ú ló tún ń dènà lílọ sí ilé-ẹ̀kọ rẹ̀. Ṣebí, ẹni tí kò bá sí nílé ni ewúrẹ̀ rẹ̀ máa ń bí ọ̀kan. Ì bá jẹ́ pé ìyá Àlàbá dúró nílé ọkọ tí òun pẹ̀lú bàbá rẹ̀ mójútó ọmọ wọn, wàhálà ì bá má ti dé bá ọmọ náà, kódà àwùjọ kò bá tí jẹ nínú èso kíkan náà. Ẹ jẹ́ á wo ọ̀rọ̀ orogún ìyá Àlàbá yìí:

> Bàbá Ìdáyá, ẹ ẹ̀ jẹ́ kí ọmọ yìí bá mi gbé àtẹ lọ sí ọjà lónìí? Òní lọjà Ìmíní. Bó bá ṣe pé mo ru gbogbo àtẹ mi lọ sọ́jà níjẹsàn-án ni, abẹ́rẹ̀ ǹ bá má ṣẹkù ní gbogbo àtẹ ọ̀hún. Ilé-ìwé rẹ̀ ńkọ́? Aṣọ ló fọ̀ títí lánàá tí ilẹ̀ fi sú, kò yọjú sí ilé-ìwé. Ṣe kò tún ní lọ lónìí ni? Họwù, kí ẹ máa pọ́n jẹ̀bẹ̀ lékìísà báyìí? Ìwọ dákun o-jàre ọkọ̀ọ̀ mi, bá mi gbé e rọjà. O ó kúkú pààsì, mo jẹ́rìí rẹ. Ìwé kẹrin ò kúkú le tó bẹ́ẹ̀. Dákun ọkọ ìyá mi. *(Atótó Arére*, O.I. 13).

Kẹ̀rẹ̀kẹ̀rẹ̀ bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ ni ojú Àlàbá fi yọ tán ní ilé-ẹ̀kọ́. Kì í kúkú ṣe pé òun náà kò fẹ́ kọ́ ẹ̀kọ́, àmọ́ ìyá rẹ̀ tó lè jẹ́ olùgbèjà fún àyànmọ́ rẹ̀ kò sí níbẹ̀. Wọn sì ní ohun tí a bá fi sílẹ̀ ni ewúrẹ́ ń gbe, mójútó nǹkan rẹ! Àìmójútó Àlàbà ló mú-un wọnú oko ìparun lọ. Yàrá ìkàwé kẹrin nílé ẹ̀kọ́ alákòọ́bẹ̀rẹ̀ ló ti figi gún ẹ̀kọ́ rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí a ṣe rí i nínú ayọlò òkè yìí. Òun nìkan kọ́ èyí kóbá ní àwùjọ, ẹni tí kò rà san sí lọ́jọ́ iwájú.

**3.5. Ìbáṣepọ̀ Ojúṣe Òbí àti Àìsáàbò nínú àwọn Àṣàyàn Ìwé Ìtàn-àròsọ Yorùbá**

Ọmọ ìyá ni ajá òun ọ̀bọ́, ọwọ adẹ́tẹ̀ jọ ewé ọ̀dúndún. Lóòótọ́ ni orísun àti àwọn okùnfà àìsáàbò pọ̀ jántìrẹrẹ ṣùgbọ́n olóri láàárin wọn ni àwọn ìwà-àìtọ́ tó wà ní àwùjọ tó ń ṣe okùnfà àìsáàbò. Àìsáàbò yìí ló wá ń pagi dínà ìlọsíwájú, ìdàgbàsókè àti ìgbáyé-gbádùn láwùjọ àti ní orílẹ̀-èdè lápapọ̀. Bí àìsáàbò ti ń ṣe ìdinà ètò ààbò tó jíire láwùjọ náà ni àwọn òǹkọ̀wé ìtàn-àròsọ Yorùbá tí a ṣà yàn fún iṣẹ́ ìwádìí yìí ṣe gbé wọn kalẹ̀ nígbà tó jẹ́ pé aṣàfihàn fún àtúntò àwùjọ ni wọ́n. Àwọn ìwà-àìtọ tó forí mulẹ̀ sí àwùjọ tó hàn nínú àwọn ìwé ìtàn-àròsọ yìí ni olè jíjà, tẹ́tẹ́ títa, òwò nàbì, ẹgbẹ́kẹ́gbẹ́, ìbánidọ́rẹ̀ẹ́ oníbàlòpò àwọn ọ̀dọ́binrin àti ọ̀dọ́kùnrin àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Gbogbo àwọn ìwà àìtọ́ yìí ló ṣe atọ́nà fún àìsáàbò lọ́nà kan tàbí òmíràn tí a bá fi ojú ṣùnnùkùn wò wọ́n dáadáa.

Ẹgbẹ́kẹ́gbẹ-kíkó láàárin àwọn ọ̀dọ́ jẹ ọ̀kan lára àwọn okùnfà àìsáàbò. Fọ́gò nínú ìwé ìtàn-àròsọ *Ayé Dayé Obìnrin* ti ní àwọn ojúgbà rẹ̀ tí wọ́n jọ ń da ìgboro rú. Nígbà tí iṣẹ́ dé láti ọ̀dọ̀ Ọnọrébù, kò bèṣùbẹ̀gbà, àwọn ẹgbẹ́ rẹ̀ yìí ni ó ṣà jọ láti lọ da ilé ìgbìmọ̀ aṣòfin rú. Ì bá jẹ́ pé Ọlámìídé àti Adémídé kò tíì dara pọ̀ mọ́ ẹgbẹkẹ́gbẹ́ láti ilé-ẹ̀kọ́ girama ni, wọn kò bá ti sí lára àwọn tí Fọ́gò máa kó jọ fún iṣẹ́ àlùsì tí Ọnọrébù bẹ̀ wọ́n. Ẹgbẹkẹ́gbẹ́ ló ń ba ìwà rere àwọn ọ̀dọ́ wọ̀nyí jẹ́ tí wọ́n fi gbà sí Ọnọrébù lẹ́nu láti lọ jíṣẹ́ dé-tòru-tòru bẹ́ẹ̀. Fún ìdí èyí, fífi ẹ̀mí ṣòfò àti ìdàrúdàpọ̀ tó mú ẹ̀mí àwọn ènìyàn sọnù láwùjọ gẹ́gẹ́ bó ṣe hàn níhìn-ín:

> Ohun tí wọ́n wá rò kọ ni wọ́n bá. Àwọn ẹ̀ṣọ́ aláàbò ilé ìgbìmọ̀ aṣòfin fìjà pẹẹ́ta pẹ̀lú wọn. Wọ́n ṣe ọmọ Ológun kan àti ọlọ́pàá mẹ́ta lọ́ṣẹ́ lóòótọ́ ṣùgbọn mẹ́fa lára wọn ló ṣubú lójú ijà. Olúmìídé Àíkí náà wà lára àwọn jàǹdùkú tó ṣubú lójú ìjà! Àwọn agbófinró rí mẹ́jọ mú lára wọn ṣùgbọ́n àwọn yòókù ráàyè sálọ… (*Ayé Dayé Obìnrin,* O.I. 128).

Ohunkóhun àti ìṣẹ̀lẹ̀-kí-sẹ̀lẹ̀ tó bá ti ń da omi àlááfíà àwùjọ rú débi pé ẹ̀mí àwọn ènìyàn kò dè, débi pé ọkàn wọn kò balẹ̀ àti pé ó kó wọn sínú páká-leke nítorí ẹ̀rù kí wọ́n má bà á ikú pàdé tàbí ṣòfò ẹ̀yà ara wọn ni à ń pè ní àìsáàbò. Ǹjẹ́ àìsáàbò kàn lè ju eléyìí tí ó mú ẹ̀mí àwọn ọ̀dọ́ mẹ́fà lọ, eléyìí tó jẹ kí àwọn ẹ̀ṣọ́ aláàbò farapa àti eléyìí tó jẹ́ kí àwọn ọ̀dọ́ farapa. Kódà, àwọn ọ̀dọ tó sálọ bí jàǹdùkú kò tó ẹlẹrú rẹ̀ tí yóò fara hàn nínú ìlú. Oúnjẹ kan ni wọ́n á sá máa jẹ níbi tí wọ́n sá lọ. Láti ara èyí, wọn á tún dá ẹgbẹ ọ̀ràn mìíràn sílẹ̀ nínú aginjù tàbi ibi tí wọ́n sá lọ láti máa ṣe àwọn ará ìlú lọ̀ṣẹ. Báyìí ni ìjínigbé ti máa ń bẹ̀rẹ̀ tàbí olè jíjà nípasẹ̀ dídá àwọn ènìyàn lọ̀nà. Bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀, àìsáàbò ẹ̀mí, dúkìá àti àìfọ̀kànbalẹ̀ yóò tẹ̀síwájú nínú àwùjọ nítorí àṣìṣe òbí àwọn ọmọ yìí nípasẹ̀ àìṣe ojúṣe wọn.

Bákan náà, Fẹ̀móò jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ọmọ ẹgbẹ́ òkùnkùn tó darapọ̀ mọ́ wọn nítorí àkọ̀yìnsí àwọn òbí rẹ̀. Fẹ̀móò rí àwọn ẹgbẹ́ òkùnkùn gẹ́gẹ́ bí agbanisílẹ̀ lọwọ́ ewu lọ́jọ́ ogun bá le. Àti pé, àwọn iṣẹ́ kéékèèké tí wọ́n máa ń ṣe a máa mówó wọlé fún wọn. Nígbà tí ìyá Atinúkẹ pè é láti mọ irú ènìyàn tó jẹ́ la rí i pé ẹlẹ́gbẹ́ òkùnkùn ni. kò sí ẹni tó mọ̀ ọ́n sí olè àti alọnilọ́wọ́gbà àfi ìgbà tí ọwọ́ pálábá wọ́n segi. Tinúkẹ náà kò bá sí wàhálà, kò bá kó sọwọ́ Fẹ̀móò tí yóò dá egbò ayérayé sí ara rẹ̀ tí ìyá rẹ̀ kò bá tètè ṣe bí òbí rere. Ìdí nìyí tó fi jẹ́ pé ẹleyà ni Tinúkẹ́ àti Mágírẹ́ẹ̀tì ìya rẹ̀ ń fi Fẹ̀móò ṣe nígbà tí wọn lọ jalẹ̀ tí ọwọ́ tẹ̀ òun àti àwọn akẹgbẹ́ rẹ̀. Fún ìdí èyí, kò sí àní-àní pé, ẹgbẹ́kẹ́gbẹ́ pàápàá jùlọ ẹgbẹ́ òkùnkùn láàárín àwọn ọ̀dọ́ wà lára ọ̀kan pàtàkì nínú okùnfà àìsáàbò ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà. Bí ìjọba bá lè fọwọ́ gidi mú àdínkù ẹgbẹ́ òkùnkùn, ó dánilójú pé àìsáàbò máa dínkù díẹ̀ láwùjọ. Ọ̀nà wo ni eléyìí fi lè ṣeé ṣe kò ju mímúra sí ojúṣe òbí lọ.

Ohun tó jọ eléyìí wáyé nínú *Atótó Arere* nílé Sámínù. Sámínù ṣe àpèjẹ láti dáwọ̀ọ́ ìdùnnú dídé tí Àlàbá ti ọgbà ẹ̀wọ̀n dé lẹ́yìn ọdún méje. Àwẹ̀jẹ-wẹ̀mu ń wáyé tí gbogbo nǹkan sì ń lọ ní ìrọwọ́rọsẹ̀ láàárin àwọn elérè àti àwọn ọmọ ẹgbẹ́-olè Sámínù tó kó sòdí. Ibẹ̀ náà ni wọ́n wà tí ìjà fi bẹ́ sílẹ̀ láàárín àwọn ọmọ ìsọta. Bí wọ́n ṣe ń gún ara wọn ní ìgò ni wọ́n ń ju ara wọn ní àga. Àwọn tó farapa farapa, àwọn tó gbẹ́mìí mì lójú ẹsẹ̀ gbẹ́mìí mì. Kódà, eré ni àwọn eléré ọjọ́ náà sá kúrò lójú agbo, ṣùgbọn nígbà tí àwọn ọlọ́pàá fẹ̀yín pọn Sámínù ti wọn bò ó láṣìírí ṣíṣe àlàyé ọ̀rọ̀ náà ni àgọ̀ ọlọ́pàá. Ọ̀gá ọlọ́pàá nìkan ló dúró gba ẹ̀gúnjẹ. Àpẹẹrẹ èyí hàndé nínú àyọlò yìí:

> Orí ìjókòó nínú ilé ni olórí ọlọ́pàá wà tí ọkọ̀ akóyanrìn kan fi dé, tí ó kó àwọn tí ìjàm̀bá ṣe lọ, a kò mọ ibi tó kó wọn lọ. Ẹ̀ẹ̀keji tó sì pààrà, iyanrìn ló kó bọ̀, tó já yanrìn náà lé orí ibi tí wọ́n ti pagbo ijó tẹ́lẹ̀.
> (*Atótó Arére,* O.I. 124).

Èwo nínú àwọn ènìyàn tó wà ní agbègbè ilé Sámínù ló lè sùn forí lé òṣùká ní òru ọjọ́ náà? Ó dánilójú pé nínú ìfòyà àti ìkọ́kàn-sókè ni wọn yóò wà. Ẹni tó kú ti kú, àwọn tó farapa ti bá tiwọn lọ. Ìgbé-ayé àwọn ọmọ ìsọta ń tẹ̀síwájú. Níbi àpéjẹ ọjọ́ yìí náà ni Fátóyè ti mú ìròyìn owó tó dé Báǹkì Ìlàrẹ́ lọjọ́ náà tọ àwon Sámínù wá. Ìròyìn yìí ló di ogun, ló di ọ̀tẹ̀. Òun náà ló sọ Sámínù àti àwọn ìdílé rẹ̀ àti ogunlọ́gọ̀ àwọn ìsọ̀ngbè rẹ̀ di òkú ọ̀run nítorí ọ̀nà tí Adárípọ́n àti Àlàbá gbà ṣe ètò jíjí owó ọ̀hún gbé. Mélòó la fẹ́ kà nínú eyín adípèlé ni ọ̀rọ̀ bí kíkó ẹgbẹ́kẹ́gbẹ́, olè jíjà àti àwọn ìwà-àìtọ́ mìíràn ń gbà ṣe okùnfà àìsáàbò láwùjọ. Báyìí ni àìsáàbò ẹ̀mí, dúkìá ṣe ń ṣe okùnfà àìdàgbàsókè láwùjọ wa.

Ìbáṣèpọ̀ láàárín ìwà-àìtọ́ àti àìsáàbò pọ̀ jàǹtìrẹrẹ nínú àwọn iwé ìtàn àròsọ tí a yẹ̀ wò. Kódà, ìwádìí wa fidí rẹ̀ múlẹ̀ pé láìsí àwọn ìwà-àìtọ́ yìí, Àìsáàbò máa dínkù dáadáa ní àwùjọ wa nítorí pé bí eégún ti yí wọnú ẹran tí ẹran náà yí wọnú eegun ni ìwà-àìtọ́ àti àìsáàbò wọnú ara wọn. Àìsí ojúṣe òbí sì ni okùnfà àwọn méjéèjì. Láìsí àní àní, wọ́n ní ipa mánígbàgbé lórí ìdàgbàsókè, ìgbáyé-gbádùn àti ìlọsíwájú ọmọ, ìdílé, àwùjọ àti orílẹ̀-èdè Nàìjíríà lápapọ̀.

**3.6. Àwọn Ọ̀nà tí Ipa Òbí fi lè Dẹ́kun Àìsàábò ní Orílẹ̀ èdè Nàìjíría**

Ipa tí òbí ń kó lórí ọmọ ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà lè jẹ́ sábàbí dídẹ́kun àìsáàbò ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà tí a bá fojú inú wò ó dáadáa. Lóòótọ́ ni pé ọ̀nà kan tí àwọn ènìyàn kì í sáábà fi ọkàn sí ni ipa àti ojúṣe òbí fún dídẹ́kun ìwà àìtọ́ tó jẹ́ atọ́nà fún àìsáàbò, ajẹ́bíidán ni tí a bá fojú wò ó dáadáa.

**Ẹ̀kọ́ ilé àti Ẹ̀kọ́ Ìwé:** Àkọ́kọ́ nínú àwọn ọ̀nà náà ni fífún ọmọ ni ẹ̀kọ́-ilé àti ẹ̀kọ́ ìwé tó yè kooro. Ẹ̀kọ́ jẹ́ ogún tí ó dára jù ní ayé tí gbogbo ènìyàn gbọ́dọ̀ ní pàápàá jùlọ àwọn ọmọdé tí ó máa padà di ọ̀dọ́ gẹ́gẹ́ bí igi àlọyè àwùjọ. Nígbà tí àwọn ọmọdé bá ní ẹ̀kọ́ ni wọ́n á mọ ọ̀tún yàtọ̀ sí òsì. Ìgbà náà ni wọn kò ní rí ọ̀ràn tàbí ìwà-àìtọ́ gẹ́gẹ́ bí ọ̀nà àbáyọ sí ìṣòro tí wọ́n bá ni. Lóòótọ ló jẹ́ pé àwọn ọ̀dọ́ kan wà tó kẹ́kọ̀ọ́ gboyè, tí òbí sì fi ẹ̀kọ́ kọ́ wọn dáàyè tó tọ́ tí wọn sì tún ń ṣe iṣẹ́ láabi àti òwò ìbànújẹ́ tó ń tapo sí àlà àwùjọ wa ṣùgbọ́n tí a bá gbé wọn lé àròpín à-gbé-lọ́gọ́rùn-ún, wọn kò tó nǹkan bí àwọn tí kò kẹ́kọ̀ọ́ tàbí tó jẹ́ aláàbọ̀ ẹ̀kọ́. Ọdúnjọ (1961:14) ṣe àlàyé tó ní ṣe pẹ̀lú ẹbí àti ojúṣe òbí nínú ẹ̀kọ́ àti ìdàgbàsókè ọmọ. Ó sọ pé:

Ẹ̀dá t'ó fi ọmọ sílẹ̀
Láì kọ́ lọ́gbọ́n,
T'ó ńkọ́ 'lé, t'ó sì ń k'ààṣẹ̀ jọ,
K'ó rántí pé ilé yíó di ilé ẹni ẹlẹ́ní:
Ààṣẹ̀ yíó di ààṣẹ̀ ọmọ ẹlòmíràn
Ogun yíó di ogún ẹbi ẹlẹbí gbogbo

Àbí ta ni kò mọ̀ dájú pé,
Ọmọ tí a kò kọ́
Ni yíó gbé ilé tí a kọ tà. (ìlà-5-13)

Àìsí ẹ̀kọ́ tó péye wà lára ohun tó fa ìwà-àìtọ́. Irú èyí ni ìjínigbé, ìwà sùnmọ̀mí àti ìjà ẹ̀sìn lọ́lọ́kan-ò-jọ̀kan, jàǹdùkú ètò ìdìbò, olè jíjà àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Àwọn ọ̀dọ́ ti kò kẹ́kọ̀ọ́ tàbí tó gbẹ́kọ́ ló tètè ṣeé fi tọ́rọ́ bọ sílẹ̀ lójú fún wọn láti kó jọ fún màdàrú, m̀agòmágó ìdánwò, jàǹdùkú àti àwọn ọ̀ràn yòókù. Ìdí ni pé, àwọn tí ẹ̀kọ́ dùn lára gbọ́n ṣáṣá bí eku àgó, wọn kò si fẹ́ fi ọjọ́ ọlá wọn tàfàlà. Fún ìdí èyí, ẹ̀kọ́ àwọn ọmọdé tó ń di ọ̀dọ́ láwùjọ ṣe pàtàkì fún àdínkù àìsáàbò ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà.

**Kíkọ̀biarasí Ojúṣe Òbí:** Ibi tí ayé dé lónìí ti gbẹ́gẹ́ kọjá kí òbí fi ọwọ́ yẹpẹrẹ mú ojúṣe rẹ̀ nínú ilé. Òbí gbọ́dọ̀ mọ̀-ọ́n-mọ̀ mú ojúṣe wọn ni ọ̀kúnkúndùn débi pé wọn kò fààyè sílẹ̀ fún dógbandọ́gba nínú gbígba ẹ̀kọ́ àti àìgbẹ̀kọ́ ọmọ. Èyí túmọ̀ sí pé àwọn èrò àtijọ́ pé, Ọlọ́run ní fúnni lọ́mọ tọ́, ọmọ tó gọ̀ ni tìyá ọmọ tó gbọ́n ṣáṣá ni ti baba, bí òkété bá dàgbà tán ọmú ọmọ rẹ̀ ní mu àti alágẹmọ ti bímọ tirẹ̀ tán, àìmọ̀-ọ́n-jó dọwọ́ ọmọ rẹ̀ gbọ́dọ̀ lọ sí òkun ìgbàgbé nítorí pé ohun tó wà lẹ́yìn ọfà ju òjé lọ. Nítorí náà òbí gbọ́dọ̀ mú ìjóbìí lọ́kúnkúndùn. Wọ́n gbọ́dọ̀ mú ìjóbìí ní à-mọ̀-ọ́n-mọ̀-ṣe. Dída àwọn ọmọ dá nǹkan tí ọpọlọ wọn kò tíì gbé kò sunwọ̀n. Òbí kò gbọdọ̀ méfòò pé, ó sá yẹ kí wọ́n mọ nǹkan báyìí, a gbọ́dọ̀ sọ fún wọn ní gẹ́gẹ́ bí ìyá Atinúkẹ́ nínú *Ìrìnàjò Ìfẹ́*. Òbí kò gbọdọ̀ torí iṣẹ́ fi ojúṣe wọn dá ọmọ-ọ̀dọ̀, ipa oníkálùkù kò jọ ara wọn. Iṣẹ́ àjíṣe, iṣẹ́ àṣesùn tó ń gba ojúṣe òbí lọ́wọ́ wọn fún ọmọ-ọ̀dọ̀ gbọ́dọ̀ dínkù tí a bá fẹ́ ṣe àdínkù ìwà-àìtọ́ tó jẹ́ olórí atọ́nà fún àìsáàbò láwùjọ. Òbí gbọ́dọ̀ mọ ibi tí ọmọ ń gbé, iṣẹ́ tó ń ṣe àti àwọn tó ń bá rìn. Pẹ̀lú eléyìí, àwọn ọ̀dọ́ á jẹ́ ohun àmúyangàn láwùjọ dípò irinṣẹ́ olè jíjà, jàǹdùkú, òwò àgbèrè, màgò-mágó ìdánwò àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

**Ìfidímúlẹ̀ Òfin:** Aìfidímúlẹ̀ òfin náà wà lára àwọn ohun tó ń fa àìṣe ojúṣe òbí, eléyìí tó ń fa ìwà àìtọ́ láwùjọ. Gẹ́gẹ́ bí èrò Kiral (2019:131), púpọ̀ nínú àwọn ènìyàn kò tilẹ̀ mọ̀ pé òfin wà tó de ojúṣe tí òbí gbọ́dọ̀ ṣe lórí ọmọ. Òfin ẹka tó ń rí sí ètò-ẹ̀kọ́ orílẹ̀-èdè Nàìjíríà ti ọdún 2004 ṣe àgbékalẹ̀ àwọn àlàkalẹ̀ àti òfin tó de ẹ̀kọ́ ọmọdé láwùjọ láti dènà ìwà àìtọ́. Èyí fi hàn pé, àìfidímúlẹ̀ òfin lọ́dọ̀ àwọn ìjọba ń ṣe àkóbá fún ìgbésí-ayé àwọn ọ̀dọ́ nítorí pé ọmọ tí a kọ̀ tí a kò kọ́ ló máa padà wá di ọ̀dọ́ tí yóò di eegun ẹja sí àwùjọ lọ́rùn. Eléyìí tako òfin nípa ètò-ẹ̀kọ́ ọdún 2004 tó sọ pé dandan ni owó orí, túláàsì ni aṣọ ìbora ni ọ̀rọ̀ ẹ̀kọ́ jẹ́ fún àwọn ọmọ láti ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ títí dé ilé-ẹ̀kọ́ girama kékeré. Láìṣe èyí, ogun ìjínigbé, ìwà sùnmọ̀mí, olè jíjà àti àwọn ìwà àìtọ́ mìíràn láwùjọ jẹ́ èso àìṣe ohun tó tọ́ lọ́dọ̀ àwọn òbí àti ìjọba eléyìí tí ìbọn àti agbára àwọn ológun nìkan kò lè ká.

**4. Àgbálọgbábọ̀**

Iṣẹ́ ìwádìí yìí ṣe àwárí ìmọ̀ nípa ojúṣe àti ipa òbí lórí àwọn ọmọ àti ọ̀dọ́ nínú àwọn ìwé ìtàn-àròsọ Yorùbá gẹ́gẹ́ bí aṣàwòta ìṣẹ̀lẹ̀ tó ń jẹ jáde nínú àwùjọ. Ó fi hàn pé púpọ̀ nínú àwọn ìwà-àìtọ́ tó ń jẹ jáde láwùjọ ló ti ara àìṣe ojúṣe òbí àti ìjákulẹ̀ àwọn òbí lórí ojúṣe wọn lórí ọmọ ti bẹ̀rẹ̀. Orísìí bátànì mẹ́ta ni àìṣe ojúṣe òbí ń gbà jẹ jáde. Èyí ń fa ìwà àìtọ́, ti ìwà-àìtọ́ ń fa àìsáàbò àti àìgbáyé-gbádùn, ti àìsáàbò sì ń fa àìdàgbàsókè tí ó jẹ́ àtubọ̀tán àti àyọrísí rẹ̀. Fún ìdí èyí, a fi àwọn ìwé ìtàn-àròsọ Yorùbá méje ṣe òdiwọ̀n àwùjọ àti orílẹ̀-èdè Nàìjíríà lápapọ̀ láti ṣe àgbékalẹ̀ àti àpèjúwe àwọn ìwà-àìtọ́ tó ti ara àìṣe ojúṣe òbí jáde, àtubọ̀tán àwọn ìwà-àìtọ́ yìí lórí ọ̀dọ́, ìdílé, àwọn òbí àti àwùjọ àti ọ̀nà àbáyọ sí ìṣòro àìṣe ojúṣe òbí, àìsáàbò nínú àwùjọ, eléyìí tó máa mú kí ìfọ̀kànbalẹ̀, ìgbáyé-gbádùn, àtúnṣe orúkọ tó díbàjẹ́ àti ìdàgbàsókè jọba ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà nítorí pé, ogun ìjínigbé, òwò àgbèrè, olè jíjà, jìbìtì lílù, màgò-mágó ìdánwò ti agbára ìbọn àti ẹ̀wọ̀n kò tí ì ká, ojúṣe òbí ṣíṣe nìkan ló lè ṣẹ́gun wọn. Iṣẹ́ ìwádìí yìí wá dá a lábàá pé ẹ̀kọ́ nípa ojúṣe òbí yẹ kó wà nínú kòríkúlọ́ọ̀mù ilé ẹ̀kọ́ girama. Bákan náà, òfin tó wà nílẹ̀ nípa ṣíṣe àti àìṣe ojúṣe òbí gbọ́dọ̀ múlẹ̀ láti dènà àìsáàbò tó ń pagi dínà ìdàgbàsókè orílẹ̀-èdè wa. Èyí fi hàn pé àwọn òǹkọ̀tàn ìtàn-àròsọ Yorùbá kò dágunlá

sí ọ̀rọ̀ ìlọsíwájú àti ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ. Alátinúdá ni wọ́n lóòótọ́ ṣùgbọ́n wọ́n ní àwùjọ lọ́kàn gẹ́gẹ́ bí aṣàtúnṣe àwùjọ ní ìbámu pẹ̀lú ìhà tí àwọn agbátẹ̀rù tíọ́rì ìmọ̀-ìbára-ẹni-gbé-pọ̀ láwùjọ kọ sí lítíréṣọ̀.

**Ìwé Ìtọ́kasí**


Abífárìn, O. àti Bello, S. A. (2014). The Legal Framework of Parental Responsibility in Nigeria. *Nigeria Journal of Food, Drug and Health Law*, 51(7), 9-31.

Adéyẹmí, L. (2006). *Tíọ́rì Lítíréṣọ̀ ní èdè Yorùbá*. Ìjẹ̀bú-Òdé Shebíotimọ̀ Publications.

Ajíbọ̀lá, J. O. (2016). Economic Growth Amidst Insecurity: The Nigeria Experience Nigeria. *Research Journal of Finance and Accounting.* www.iiste.org.7(7).

Akinlabí, B. (2016). *Ìrìnàjò Ìfẹ*. Ìbàdàn Ebby Publishers.

Awẹ́, D. (2015). *Omi Inú Ẹkù*. Iléṣà Elyon Publishers.

Anayochukwu, H.N.,Zain, M.M.and Halim, A.(2022). The Problem of Terrorism and Insecurity in Nigeria and its Consequences on National Development. *International Journal of Academic Research in Business and Social Sciences.*12(10),1-15.https://hrmars.com/papers submitted/14148/the-problem-of-terrorism-and-insecurity-in-nig.

Blustein, J. (1997). Procreation and Parental Responsibility. *Journal of Social Philosophy,* 28(2), 79-86.

Education Unicef (2020) unicef.org/Nigeria/education. https://ndlink.org/wp-content/uploads/2019/06/National-Yoth-Policy2019-2023-

Escarpit, R. N (1968). *Sociologie de La Literature Par Robert Escarpit*: France Press Universatiares.

Fádíyà, Ó. (2004). *Ọ̀mọ Ẹni ò ṣèdí Bẹ̀bẹ̀rẹ̀*. Ìbàdàn Feather & CapBook Services.

Fadipe, N. O. (1970). The Sociology of the Yoruba, Ibadan University Press.

Federal Ministry of Education (2004). Compendium of Education Sector Laws of Nigeria, (3)1.

Fogarty, E. and Evans, D.G. (2009). *The Common Roles of Fathers: The Five Ps.* A Series of the Department of Family, Youth, and Community Sciences, Florida Cooperative Extension Service, Institute of Food and Agricultural Sciences, University of Florida. http://edis.ifas.ufl.edu.

Kiral, B. (2019). The Rights and Responsibilities of Parents According to the Views of Teachers. *Asian Journal of Education and Training*, 5(1), 121-133.

Ọdúnjọ, J.F. (1961). *Àkójọpọ̀ Ewì Aládùn*. Lagos Longman.

Ògúngbadé, A. (2009). *Ogé Ré Mi Fọ́*. Ògúngbadé-Gbénga Printing Press.

Ògúnṣínà, B. (2006). *Sociology of the Yorùbá Novel: An Introduction*. Ìlọrin Integrity Publication.

Òkédìjí, O. (2005). *Atótó Arére*. Àtúnṣe Kẹrin. Ìbàdàn University Press PLC.

Olúṣọlá, A. (2017). *Ayé D'ayé Obìnrin.* Pathfinder Global Educational Publishers Limited.

Olúṣọlá, Ẹ. (2014). *Sóoróyè*. Pathfinder Global Educational Publishers Limited.

Omede, J. (2012). Reformatting Nigerian Secondary and Post-secondary Education to meet Unemployment and Security Challenges in Nigeria in the 21st Century. *Research Journal in Organizational Psychology and Educational Studies (RJOPES),* https://www.emergingresource.org.

Omede, J. àti Omede, A. (2015). Terrorism and Insecurity in Nigeria: Moral, Values and Religious Education as Panaceas. *Journal of Education and Practice*, (6)11, 1735-2222.

Onífádé, C., Imhonop, P. D. àti Urim, U. M. (2013). Addressing the insecurity challenges in Nigeria: The Imperative of Moral Values and Virtue Ethics, *Global Journal of Human Social Science Political Science,* 13 (2), 89-106.

Rosenberg, J. and Bradford, W. (2015). *The Importance of Fathers in the Healthy Development of Children.* US Department of Health and Human Services. Children's Bureau Office on Child Abuse and Neglect. https://www.chldwelfare.gov.

Strbová, M. (2004). Uloha a podstatadobréhootcovstva. *Vychovavate*, 50(9), 17.

Udoh, E. W. (2015). Insecurity in Nigeria: Political, Religious and Cultural Implications. *Journal of Philosophy, Culture and Religion. www.iiste.org.* 5 (2), 23–38.